# IWAASU PAULU LORI OKE AREOPAGU

**Iṣe Awọn Apọsteli 17:1 - 34**

**ẸKỌ 335 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Ninu rẹ̀ li awa gbé wà li ãye, ti awa nrin kiri, ti a si li ẹmi wa" (Iṣe Awọn Apọsteli 17:28).**

**Wiwaasu Ihinrere**

Paulu ati Sila kò rẹwẹsi bi wọn tilẹ ni wahala. Lẹẹkan si i, wọn tun lọ si awọn ilu miiran gbogbo pẹlu ihin ayọ̀ ti igbalà. Ni ilu Tẹssalonika, wọn ri sinagọgu awọn Ju kan nibi ti Paulu gbé ni anfaani lati waasu. Ọpọ awọn Helleni lọkunrin ati lobinrin, gba ọ̀rọ ti Paulu sọ nipa ijiya ati ajinde Kristi kuro ninu okú gbọ́.

Ṣugbọn diẹ ninu awọn Ju bẹrẹ si jowu nitori pe ọpọ eniyan feti si ti Paulu. Ni ọjọ kan awọn jagidijagan eniyan dá rogbodiyan nla silẹ ninu ilu, wọn si n wá Paulu ati Sila. Wọn rò pé awọn ajihinrere wọnyi wà ni ile Jasoni, ṣugbọn nigba ti wọn kò ri wọn nibẹ, awọn eniyan buburu wọnyi mú Jasoni lọ siwaju awọn alaṣẹ ilu. Awọn akorira otitọ wọnyii n kigbe pe, "Awọn wọnyi ti o ti yi aiye po wá si ihinyi" (Iṣe Awọn Apọsteli 17:6). Wọn sọ fun awọn alaṣẹ pe Paulu oun Sila n kọ́ ni nipa Ọba ti a n pe ni Jesu. Eyi mú iyọnu nla bá awọn alaṣẹ, ṣugbọn nikẹyin wọn jọwọ Jasoni lọwọ lọ. Ṣugbọn awọn ọrẹ Paulu pinnu pe o ṣanfaani pe ki o fi ilu silẹ ki wahala miiran maa ba tun ṣẹlẹ. Ni oru Paulu oun Sila lọ si Berea, nibi ti a gbe fi tọkàntọkàn gbà wọn; nibẹ wọn waasu fun ọ̀pọ eniyan nipa Jesu.

Ṣugbọn nigba ti awọn Ju buburu ti o wa ni Tẹssalonika gbọ́ pé Paulu ati Sila n waasu Ọrọ Ọlọrun ni Berea, wọn lọ sibẹ̀ lẹsẹkẹsẹ wọn si rú awọn eniyan soke. O dabi ẹni pe Satani ki i ni itẹlọrun titi di igba ti o ba sa gbogbo ipa rẹ lati dá iṣẹ Oluwa duro. Laisi aniani, a funrugbin Ọrọ Ọlọrun ni ilu wọnyii, ani gẹgẹ bi irugbin kekere ti a gbin sinu ilẹ, yoo hù jade, yoo si dagba, yoo si so eso ninu ọkàn kọọkan ti ebi n pa.

**Ni Atẹni**

Lẹyin naa Paulu lọ si Atẹni ilu nla ti Giriki nibi ti o gbé n duro de Sila ati Timoteu lati dara pọ mọ́ ọn. Paulu kò joko kawọ́ gbera lasan ni akoko yii, gẹgẹ bẹẹ loni, ọwọ awọn ọmọ Ọlọrun kún fun iṣẹ fun Oluwa nigba gbogbo. Bi o si ti n rin kiri laaarin ilu yii, ọkàn rẹ̀ rú ninu rẹ̀ nitori ti o ri i pe ilu naa kun fun oriṣa ati awọn abọriṣa. Ẹnikan tilẹ sọ pe iye oriṣa ti ó wà ni Atẹni tayọ iye eniyan ti o wà nibẹ. Ni ojoojumọ ni Paulu n lọ sinu sinagọgu awọn Ju ati si awọn ibi itaja ti o si n waasu Jesu fun awọn eniyan.

**Oke Areopagu**

Awọn eniyan n beere pẹlu iyanu pe: iru ọlọrun ajeji lati ilẹ ajeji wo ni Paulu n sọ nipa rẹ̀ yi? Awọn miiran si wi pe: "Kili alahesọ yi yio ri wi?" Ọrọ Paulu dabi ọ̀rọ ti kò ni laari, bi ọ̀rọ were ni eti wọn. Paulu, ẹ̀kọ́ tuntun wo ni o mu wá yii? Iwọ mu "ohun ajeji wá si eti wa."

Awọn eniyan wọnyii pinnu pe ki a mu ọkunrin yii lọ si Oke Areopagu, ti i ṣe ibi-idajọ ti o ga jù lọ ni Atẹni. Ni ibi-idajọ Oke Areopagu yii, ni a mu Paulu lọ lati sọ ti ẹnu rẹ̀ niwaju awọn ti i ṣe ọjọgbọ́n ju lọ ni ilẹ Giriki. Nigba naa ni Paulu dide duro niwaju awọn ọjọgbọ́n wọnyii o si wi pe, "Bi mo ti nkọja lọ, … mo si ri pẹpẹ kan … FUN ỌLỌRUN AIMỌ̀." O wá lati sọ fun wọn nipa Ọlọrun yii gan an -- Ọlọrun ti O dá ayé ati ohun gbogbo. O ha le jẹ pe wọn kò ti gbọ́ nipa Ọlọrun ti ki i gbé inu ile ti a fi ọwọ́ kọ́? Wọn kò gbọdọ ni èrò pe Ọlọrun otitọ dabi ere wura, fadaka, tabi okuta ti a ti ọwọ eniyan ṣe. Paulu wi pe nigba kan ri Ọlọrun fara dà O si gboju fò igba aimọ̀ wọn, ṣugbọn o tó wayii; Ọlọrun paṣẹ nisisiyi fun gbogbo eniyan nibi gbogbo lati ronupiwada. Lẹyin naa Paulu sọ fun wọn eredi rẹ̀ ti wọn fi ni lati ronupiwada ẹ̀ṣẹ wọn: nitori pe Ọlọrun ti yan ọjọ kan ninu eyi ti Jesu yoo pada wá si aye ti yoo ṣe idajọ awọn eniyan nitori ohun ti wọn ti ṣe lori ilẹ aye. Paulu tẹnumọ ọ pe Ọlọrun ji Jesu dide kuro ninu okú lati jẹ́ Olugbala wọn, ati pe Oluwa kò "jina si olukuluku wa" (Iṣe Awọn Apọsteli 17:27). Bi o ba ṣoro lati ri Oluwa, ki i ṣe nitori pe o jina si wa, ṣugbọn nitori pe awa paapaa jina si I a ko si fẹ sunmọ Ọn. Ni igba gbogbo ni Oun n reti pe ki ẹlẹ̀ṣẹ ronu piwada ki o si yi pada si Oun fun idariji.

**Awọn Ẹlẹgan**

Njẹ awọn ara Atẹni gba ọrọ ti Paulu sọ yii gbọ́? Diẹ ninu awọn eniyan yii n fi ọran ajinde Jesu kuro ninu okú ṣẹfẹ. Saa fi oju inu wo bi awọn eniyan ti ṣe ainaani ti wọn si n fi otitọ ajinde, eyi ti i ṣe ireti Onigbagbọ ṣẹfẹ! Paulu kọ ọ́ pe, "Bi a kò ba si ji Kristi dide, asan ni igbagbọ́ nyin" (1 Kọrinti 15:17). Awọn miiran wi pe ki Paulu tún pada wá ni ọjọ miiran boya awọn yoo le nifẹ si ohun ti o n sọ.

Awọn ẹlomiran n rò pe bi awọn kò bá mọ pupọ nipa Oluwa ati Ihinrere, a ki yoo beere pupọ li ọwọ wọn. Awọn ọmọkunrin ati ọmọbinrin miiran rò pe o tilẹ ṣanfaani fun wọn bi wọn ba fa sẹyin ni ile Ọlọrun ki a maa ba kà pupọ si wọn lọrun nipa imọ ati imọlẹ ti wọn i ba ni nipa Ọrọ Ọlọrun. Otitọ ti o daju ni pe wọn yoo dahun fun gbogbo ododo ti a gbe kalẹ ninu gbogbo Ọrọ Ọlọrun nitori pe ododo wọnyii wà ni arọwọto wọn. Ẹ jẹ́ ki a bẹru ki a má si ṣe kuna lati lo gbogbo anfaani ti a ni lati gbọ́ ati lati kọ́ nipa ti Oluwa, nitori kò si awawi ti yoo lè gbà wá silẹ niwaju itẹ idajọ Ọlọrun ni ọjọ nla nì.

Awọn diẹ ni o gba ọ̀rọ ti Paulu sọ nipa Jesu gbọ́, a si kà awọn ọ̀rọ ti o ba ni ninujẹ wọnyii pe, "Bẽni Paulu si jade kuro larin wọn."

Ọjọ n bọ ti Kristi yoo rẹrin ti yoo si ṣe ẹ̀fẹ awọn wọnni ti wọn kọ ipe Ọlọrun. "Emi pẹlu o rẹrin idãmu nyin; emi o ṣe ẹ̀fẹ nigbati ibẹ̀ru nyin ba de" (Owe 1:26). Ọjọ ti Paulu sọ nipa rẹ̀ nì -- ọjọ naa ti Ọlọrun ti yàn ninu eyi ti yoo ṣe idajọ araye nitori ẹ̀ṣẹ wọn –wa niwaju, o si n bọ̀ wá. Ni ọjọ naa, ki i ṣe awọn ara Atẹni, Giriki, ati awọn ara Tẹssalonika ati Berea nikan ni yoo wà lai si awawi, ṣugbọn ọ̀pọlọpọ eniyan ni gbogbo agbaye ni yoo yadi niwaju Onidajọ ododo. A ti sọ itan Ihinrere fun wọn, ṣugbọn wọn sé àya wọn le. Ki Ọlọrun ran wa lọwọ lati ni eti igbọ́ ati aya igbaṣe si itan Jesu ati ifẹ Rẹ̀.

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni koko iwaasu Paulu?
2 Sọ iha ti awọn Ju ti Tẹssalonika kọ si Paulu?
3 Ki ni Paulu ṣe nigba ti o dé Atẹni?
4 Orukọ wo ni wọn pe Paulu ni Atẹni?
5 Sọ iwaasu Paulu lori Oke Areopagu?
6 Ki ni Oke Areopagu jẹ?
7 Ofin keloo ni o sọ pe a kò gbọdọ sin ère wura, fadaka, ati okuta?
8 Njẹ awọn eniyan gba ọ̀rọ Paulu gbọ́ nipa ajinde Kristi?
9 Ki ni ohun ti Paulu sọ nipa aigba ọ̀rọ ajinde gbọ́?
10 Ki ni ajinde Kristi jẹ fun wa lọjọ oni?